# PÀTÀKÌ FÚN ÀWỌN ỌDỌ́

## FÚN KÌKÌ ỌDỌ́ NÌKAN

Mary Owólabí

**PÀTÀKÌ FÚN ÀWỌN ỌDỌ́**

FÚN KÌKÌ ỌDỌ́ NÌKAN

Láti ọwọ́ Díákónì Obìnrin Mary Owólabí

Copyright © 2017

**Àṣẹ tí a Kò fún ni.**

Pé a kò fún ẹnikẹ́ni láṣẹ láti tún kọ tàbí dàkọ apá kan nínú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yálà nípa ẹ̀rọ ayárabíàṣá tàbí àwọn ọ̀nà mìíràn láì gba àṣẹ láti ọwọ́ òǹkọ̀wé; àyàfi lílò fún bìí àkàjúwe tí ó ṣe kókó.

Gbogbo àkàjúwe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a lò jẹ́ ti ìwé mímọ́ King James Version àti New Living ti Bíbélì Mímọ́.

Fún àdúrà àti ọ̀rọ̀ ìyànjú, jọ̀wọ́ pe òǹkọ̀wé:
**The Divine Message and Great Mission**

Sórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ yìí:
+2348140606077; 07055512708

Ẹ̀rọ ayárabíàṣá:
thedivinemessageandgreatmissio@gmail.com

**ISBN:** 978-978-54106-8-6

# ÌPÈ ÌRÁNṢẸ́

Ẹni tí Ọlọ́run pè tí ó sì rán láti dín èrò ìjọba èṣù kù ní kíkọsílẹ̀ nípa ìtọ́ni àti ìfihàn àtọ̀runwá àti títọ́sọ́ nà nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti tú àṣírí tí ó n darí ẹni sí ìsọdi ọ̀mìnira àti láti sìpẹ̀ fún àti láti gba àwọn ọmọ Ọlọ́run níyànjú ní gbogbo ayé, kí á ba le jèrè wọn padà sínú ìjọba Ọlọ́run tó ga jùlọ.



# ÌFIJÌ

Àkọsílẹ̀ kékeré yìí ni mo fi jì fún Ọlọ́run alágbára fún ore-ọ̀fẹ́ àti àánú Rẹ̀ lórí ayé mi. Fún ìtọ́ni àti àánú rẹ̀ tí ó mú mi jáde láti inú erùpẹ̀ ẹrọ̀, àti pẹ̀lú fún ìfẹ́ Rẹ̀ fún mi láti ní ipa ní àwùjọ àwọn ènìyàn mi. Mo yìn orúkọ mímọ́ Rẹ̀.

# ỌRỌ̀ ÀKỌ́SỌ

Ìwádìí ìsisìnyí fi yé wa wípé àwọn àpọ́n /omidan kan kàn dàbí ẹni pé wọ́n láyọ̀ nínú ìgbé ayé àpọ́n wọn, ṣùgbọ́n ní abẹ́nú ìgbé ayé àwọn àpọ́n yìí kú fún ìṣiyèméjì ara ẹni, ìdára ẹni lẹ́bi fún àjọṣepọ̀ tí ó kùnà àti àìní ìdánilójú.

Ẹ̀rù dídáwà, ọ̀rọ̀ nípa ìdáraẹnilójú, ìṣòro ti ìdánimọ̀ pẹ̀lú ìtọnà, ẹ̀dá ẹni, ọ̀rọ̀ nípa èrò inú ẹni pẹ̀lú ìbínú òun ìbẹ̀rù, àti àwọn nkan bíi ìnira nípa alárinà tàbí ní àtirí ẹnìkejì tí ó wuni, jẹ́ àwọn ìṣòro tí ó n kojú àwọn àpọ́n/omidan.

Àkọsilẹ̀ yìí ti ṣe ìlàkalẹ̀ ìṣura tí a nílò láti ní ìpìlẹ̀ tó dájú fún níní ìgbéyàwó tí ó lálàáfíà àti ẹbí tí ó dúró ire tí ó sì lè jẹ́



àwòkọ́ṣe àjọṣepọ̀ ìgbéyàwó, nípa "fífi ìpìlẹ̀ rere lelẹ̀" tí í ṣe Krístì Olúwa.

Krístì, pàtàkì igun ilé ti fi ọ̀nà àfojúsùn rere sílẹ̀ láti tán ìṣòro àwọn ọ̀dọ́ tí kò tíì gbéyàwó. "Pàtàkì fún àwọn ọ̀dọ́" sọ pé o nílò Jésù, láti ní ojọ́ ọla tí ó dára.

Ìwé yìí jẹ́ "àìgbọ́dọ̀ má kà" àti "àìgbọ́dọ̀ má nìí" fún gbogbo àwọn àpọ́n/omidan.

**Olùṣọ́àgùntàn Tim Agbeja** JP
Olùṣọ́àgùntàn Agbègbè Gbàgádà/National Finance Secretary, T A C, Nigeria.

# ÌMỌRÍRÌ

Ṣáájú ohun gbogbo, mo fi ògo, ọlá àti ọ̀lánlá fún Ọlọ́run alàáyè kanṣoṣo nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì fún bí ó ti jẹ́ àṣírí àti orísun ìmísí mi. Mo fi ìbùkún fún Aṣẹ̀dá ọ̀run òun ayé tí Ó ti mọ̀ mí láti inú ìyá mi wá, tí Ó sì ti pinnu rẹ̀ nípa ìpè àtọ̀runwá Rẹ̀ lórí ayé mi láti ní ipa lórí àwùjọ/ìran mi. Mo fi ìbùkún fún orúkọ mímọ́ Rẹ̀. Àmín.

Ọkọ mi, fún jíjẹ́ ara ìgbésí ayé mi, fún níní ipa lórí ayé àti iṣẹ́ ìránṣe mi, fún jíjẹ́ ọkọ tí ó ṣọ̀wọ́n sí ògo Ọlọ́run, mo nífẹ̀ ẹ́ yín, mo sì dúpẹ́ lọ́wọ́ yín.

Sí àwọn ọmọ mi, fún jíjẹ́ ara ìgbésí ayé iṣẹ́ ìránṣẹ́ mi àti pẹ̀lú fún Ọjọ́ ọ̀la tí ó dára nínú Krístì Jésù, mo nífẹ̀ẹ́ yín gan.
Sí olùbáṣisẹ́ mi, Arábìnrin Mercy



Folásadé Fákúnlé, fún gbígbà ìpè Ọlọ́run nínú ayé rẹ̀ pàápàá nínú iṣẹ́ nlá yìí, mo gbàdúrà wípé ìpinnu Rẹ̀ fún ọ àti ìdílé rẹ yíò wá sí ìmúṣẹ ní orúkọ Jésù Krístì. Àmín.

Sí bàbá mi nínú Olúwa,Olùṣọ́-àgùntàn I.G. Fákúnlé, ọdún mẹ́ta tí ẹ lò ní olú ìlú ilẹ̀ wa Àbújá láàrin oṣù kejìlá ọdún 2009 sí oṣù kẹjọ odún 2012, jẹ́ èyí tí ó ni ipa nlá lórí ìgbé ayé ẹ̀mí àti ìránṣe mi. Mo gbàdúrà pé, ẹ ó gba adé ògo ní ìkẹhìn iré ìje yín ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.

Mi ò lè ṣài dúpẹ́ lọ́wọ́ alábòjútó FCT Àbújá lọ́wọ́lọ́wọ́ yìí,Olùṣọ́-àgùntàn L.O. Ọládélé, fún àwọn ọ̀rọ̀ ìṣọtẹ́lẹ̀ wọn tí ó n ṣeni gírí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Jésù Krístì fún ayé yín.

# TÁBÌLÌ ÀKÒRÍ

Ìpè Iránṣẹ́ ... ... ... ... ... iii
Ìfiji ... ... ... ... ... ... iv
Ọ̀rọ̀ Àkóso ... ... ... ... ... v
Ìmọrírì ... ... ... ... ... vii
Tábìlì Àkòrí ... ... ... ... ix
Ìfáàrà ... ... ... ... ... x
Ìtumọ̀ àwọn Èdè ... ... ... ... xii

**ORÍ KÌN-ÍN-NÍ**
Fífi Ìpìlẹ̀ Rere Lélẹ̀ ... ... 1-14

**ORÍ KEJÌ**
Wíwá Agbára Fún Ipa Rere ... 15-24

**ORÍ KẸTA**
Àwọn Kókó Àsírí/Ero Ìparí ... 25-29



# ÌFÁÀRÀ

Ìdí pàtàkì fún kíkọ àkọsílẹ̀ kékeré yìí ni pé ó yẹ kí àwọn ọ̀dọ́, l'ọ́kùnrin àti l'òbìnrin kí wọ́n ní ìpìlẹ̀ tí ó dára tí ó sì dúró ṣinṣin, kí wọ́n ba lè gbé ìgbé ayé tí ó ní ipa ní ìran wọn. Mo ti ri wípé kò sí ìpìlẹ̀ mìíràn tí a le fi lélẹ̀ bíkòṣe nínú Krístì Jésù.

Ẹni tí ó bá n mọ ìpìlẹ̀ yìí gbọ́dọ̀ kíyèsára gidigidi. Nítorí ẹnikẹ́ni kò lè fi ìpìlẹ̀ mìíràn lélẹ̀ ju èyí tí a ti ni -Jésù Krístì. Ilé kílé tí a bá kọ́ láìní ìpìlẹ̀ tàbí tí a kò kọ́ ìpìlẹ̀ rẹ̀ dáradára, kò lè dúró pẹ́. Ohun èlò dídára yòówù tí a bá fi kọ́ ilé sórí ẹ̀rùpẹ̀ yíò bàjẹ́ yíò sì ya sọnù láìpẹ́ ọjọ́. Bí ìpìlẹ̀ ilé bá sì ṣe lágbára tó náà ni ilé tí a kọ́ sórí rẹ̀.

Kọ́ bí a tii kẹ́kọ̀ọ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn elòmíràn. Rántí pé Ọlọ́run nìkan ni ó mọ ohun

gbogbo. Ní àkókò ìgbẹ̀hìn tí a wà yìí, ìmọ̀ pọ̀ jaburata ṣùgbọ́n ọgbọ́n ṣọ̀wọ́n. Ìtumọ̀ ọgbọ́ ju wípé kí á kàn ní ìmọ̀ ohun púpọ̀ lọ. Ó jẹ́ ìṣesí pàtàkì tí ó ní ṣe pẹ̀lú gbogbo ẹ̀yà ìgbé ayé ènìyàn. Ìpìlẹ̀ ìmọ̀ ni pé kí á bẹ̀rù Olúwa, kí á fi ọlá fún Un, kí á sì fọ̀wọ̀ fún Ọlọ́run, kí á máa gbé nínú iṣẹ́ agbára Rẹ̀ kí á sì gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ Rẹ̀.

Mímọ Jésù nìkan kò tó bíkòṣe kí á gbààá lágbàtán. Ní gbígbà á, àwọn ọ̀dọ́ gbọ́dọ̀ ṣe ìfẹ́ rẹ̀ kí wọ́n sì tẹ̀lé òfin rẹ̀ gbogbo. Wọ́n gbọdọ̀ wá ọgbọ́n láti ní ipa rere lórí àwọn àwùjọ wọn nípa bíbẹ̀rù Ọlọ́run. Ìbẹ̀rù Olúwa ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ọgbọ́n. Nítorí náà gẹ́gẹ́ bí ọ̀dọ́, o nílò láti bẹ̀rù Ọlọ́run kí o bá lè rí ọgbọ́n rẹ̀ gbà láti jọba lórí ìran rẹ àti ayé rẹ̀.



# ÌTUMỌ ÀWỌN ÈDÈ

**Níní Ipa:** Èyí jẹ́ láti mú ènìyàn ṣe ohun kan; láti yí àwọn elòmíràn padà sí rere tàbí búburú, láti fún ènìyàn ní ìfọwọ́tọ́ pàtàkì.

**Ayé:** Èyí túmọ̀ sí gbogbo ilé, ènìyàn, ibi gbogbo àti ohun tí ó wà lórí rẹ̀. O lè ní gbogbo ayé ní àtẹ́lẹṣẹ̀ rẹ. Bíbélì wípé "Ẹlẹ́dàá rẹ fi ayé ṣe àpótí ìtisẹ̀". Ìwọ náà sì lè ṣe bẹ́ẹ̀ nítorí ọmọ rẹ̀ ni ìwọ í ṣe. Kìkì nípa ìgbọ́ràn sí àṣẹ rẹ̀ o lè ṣe bẹ́ẹ̀. O lè jọba lórí ayé rẹ.

## ORÍ KÌN-ÍN-NÍ

# FÍFI ÌPÌLẸ̀ RERE LÉLẸ̀

**"Nítorí ìpìlẹ̀ mìíràn ni ẹnìkan kò lè fi lélẹ̀ ju èyí tí a ti fi lélẹ̀ lọ, tí í ṣe Jésù Krístì."** 1Kor 3:11. **"Bí ìpìlẹ̀ bá bàjẹ́, kí li olódodo yíò ṣe?"** Orin Dáfídì 11:3.

A ní láti kọ́ ayé wa/ọjọ́ ọ̀la wa lórí JÉSÙ Krístì, Òun ni àpáta agbára. 1Kor 10:4c. Ní kíkọ́ ayé rẹ, iṣẹ́ àyò rẹ, ìdílé rẹ, ìgbéyàwó rẹ, o gbọ́dọ̀ dúró kì o sì kọ́ ọ sórí Jésù tí í ṣe ìpìlẹ̀ ohun dídára gbogbo. Òun ni Ọlọ́run ìpìlẹ̀ rere gbogbo. Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti gba Ọlọ́run láàyè kí Ó fi ìpìlẹ̀ rere lélẹ̀ nínú ayé rẹ. Ó sì ṣe kókó pẹ̀lú kí o wà ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú rẹ̀. Èyí ni pé kí o wà ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú olùkọ́ ilé náà. Nígbànáà ni Ọlọ́run yíò dunnú sí ìbáṣepọ̀ Òun tìrẹ, Òun yíò sì ṣetán láti ṣe ohunkóhu fún ọ.



O ní láti kọ́lé lée lórí - Jésù. Òun ni ìpìlẹ̀ àti ọ̀mọ̀lé ọjọ́ ọ̀la tí ó dára tí o fẹ́ ní. Jẹ́ k í ó mọ ọ́, tún un mọ, kí ó sì gbé agbára wọ̀ ọ́. Kò tíì pẹ́jù, o lè tún ayé rẹ àti ọjọ́ ọ̀la rẹ mọ. O gbọ́dọ̀ mọ lé orí ìpìlẹ̀ tí ó yè koro tí í ṣe Krístì Jésù, láìsí rẹ̀, o kò lè ní ìpìlẹ̀ míràn.

Ìpìlẹ̀ rere tí ó sì yè koro nínú Krístì jẹ́ ohun àmúyẹ, Krístì sì ni àmúyẹ fún àṣeyọrí nínú ayé rẹ àti fún ọjọ́ ọlá rẹ. O ràn wọ́n lọ́wọ́ láti kó owó jẹ ní ibi iṣẹ́ rẹ, o sì n kígbe nípa ìwà àwọn tí ó n ṣe irú rẹ̀ ní àyíká rẹ. Ìwọ a máa bínú, kò sì n pé kí wọ́ n tó ṣẹ̀ ọ́, síbẹ̀ ò n dá àwọn èyìyàn àyíká rẹ lẹ́bi nígbàkúgbà tí wọ́n bá hùwà bẹ́ẹ̀. O ní láti mọ̀ wípé ohun tí o bá gbìn ni ìwọ yíò ká.

Ẹ jẹ́ kí á sọ òtítọ́ ọ̀rọ̀, a kò lè gan Ọlọ́run. O máa n sọ lóòrèkóòrè wípé àwọn ọ̀rẹ́ rẹ kìí sọ ọ̀títọ́. Njẹ́ ìwọ́ n sọ? Nínú ọkàn rẹ, dá ara rẹ lóhùn; ṣe ìwọ́ n sọ? Àwa fúnra wa

ni à n fa ohun búburú tí ó n ṣẹlẹ̀ ní àyíká wa. Mo mọ̀ wípé o mọ̀ púpọ̀ nínú ìwé mímọ́, ṣùgbọ́n báwo ni ọkàn rẹ ṣe mọ́ sí? Bí ọkàn rẹ ti mọ́ tó, sọ nípa títóbi àti ìjìnlẹ̀ agbára òun ore-ọ̀fẹ́ tí o ní nínú àjọṣepọ̀ rẹ pẹ̀lú Ọlọ́run. Bí o ṣe mọ ọ̀mọ̀lé to, ni ó sọ bí ó ṣe lè kọ́ ọ̀ láti mọ ayé rẹ. **"Bíkòṣepé OLÚWA bá mọ́ ilé náà àwọn tí n kọ́ ọ n ṣiṣẹ́ lásán: bíkòṣepé OLÚWA bá pa ìlú mọ́, olùṣọ́ jí lásán."** Orin Dáfídì 127:1.

A kò lè jẹ́ ọ̀mọ̀lé bí Krístì ò bá tíi kọ́ tẹ́mpìlì rẹ̀ sínú ayé wa. Báwo ni o ṣe jọ̀wọ́ ara rẹ fún Jésù Krístì sí? Bẹ̀ẹ́ ò n ráhùn nípa àwọn ọ̀rẹ́ rẹ, àfẹ́sọ́nà rẹ tàbí àwọn òbí rẹ pé wọn kó rẹ ara wọn sílẹ̀ tàbí fọwọ́sowọ́ pọ̀.

N kò fi ẹ̀sùn kàn ọ́, ṣùgbọ́n mò n rò wípé, bóyá bí Ọlọ́run bá ti ní àyè nínú rẹ, ohun gbogbo ìbá ti bọ̀ sípò. Bóyá tí o bá bá Ọlọ́run làjà, Òun yíò fún ọ ní ọ̀rọ̀ ọgbọ́n láti yanjú ohun tí ó yí ọ ká. Ìpìlẹ̀ wa pẹ̀lú




Ọlọ́run níí ṣe pẹ̀lú ohun gbogbo tí ó n ṣẹlẹ̀ ní àyíká wa. Bẹ́ẹ̀ni. Mo mọ̀ pé ohun gbogbo tàbí púpọ̀ nínú ohun t ó yí ọ ká ni ó n lọ déédé. Ṣùgbọ́n ọ mọ̀ nínú ọkàn rẹ pé ìwọ́ àti Ọlọ́run nìkan ni o mọ àwọn ibi tí o ti n bá Ọlọ́run jìjàkadì nínú ayé rẹ. Bóyá o kò tíì jọ̀wọ́ fún Un ní kíkún tàbí o lérò wípé Ó wà pẹ̀lú rẹ tí Òun sì n fẹ́ láti mú ọ jinlẹ̀ si nínú Rẹ̀. Ó ṣe pàtàkì fún wa láti mọ̀ wípé láìsí ìpìlẹ̀ tí ó dára, a kò lè kọ́ ohun yòówù tí a pinnu láti kọ́. Láìsí ìpìlẹ̀ tí ó dára tí ó sì yè koro, a kò lè kọ́ ayé wa àti ọjọ́ ọ̀la wa. Ayé tí a bá kọ́ sórí ìpìlẹ̀ tí kò dára tàbí búburú yíò dà wó dandan nii. Irú ayé bẹ́ẹ̀ yíò ní ìdojúkọ, ìṣubú, nṣe ni yíò ma mì.Níbo ni ìwọ n kọ́ ayé àti ọjọ́ ọ̀la rẹ lé lórí?

**"Nítorí ìpìlẹ̀ míràn ni ẹnìkan kò lè fi lélẹ̀ ju èyí tí a ti fi lélẹ̀ lọ, tí í ṣe Jésù Krístì."** 1Kor 3:11
**"Bí ìpìlẹ̀ bá bàjẹ́, kí li olódodo yíò ṣe?"** Orin Dáfídì 11:3

**Kí o báa lè kọ́ ayé àti ọjọ́ ọ̀la rẹ, o ní láti ṣe àwọn nnkan wọ̀nyí:**

**Ohun tí àgbọdọ̀ ṣe**






**a. Ṣe ìṣirò ohun tí yíò ná ọ**



Ni kíkọ́ ayé àti ọjọ́ ọ̀la rẹ nínú Krístì, o gbọ́dọ̀ ṣe ìṣirò ohun tí yíò ná ọ. Èyí ni pé, kíni àwọn ohun tí yíò ná wa láti jẹ́ Krístẹ́nì? O gbọ́dọ̀ kọ ayé àti iṣẹ́ rẹ sílẹ̀; nípa pé kí á máa:

- Gba agbára ti ayé yìí. (Ilé ayé yìí jẹ́ ayé agbára, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ l'a sì nílò agbára láti tẹ̀síwájú àti láti ṣe àṣeyọrí). O nílò láti ṣe àwárí agbára tòótọ́ nípasẹ̀ agbára Ẹ̀mí Mímọ́ láti tẹ̀síwájú.

- Ṣe bí ayé tí n ṣe. Bíi fífẹ́ ìyàwó pẹ̀lú agbára òkùnkùn, bíbí ọmọ nípa bíbéèrè lọ́wọ́ ayé, níní ọrọ̀ nípa ṣíṣẹ́ṣó. Gbogbo èyí jẹ́ ọ̀nà búburú láti ṣe àkójọ.
- Tẹ̀lé ara sùgbọ́n kí á gbọ́ràn sí ọrọ Ọlọ́run láìsí àníànì.
- Ṣe ìfẹ́ inú wa lòdì sí ìfẹ́ ti Ọlọ́run ní gbogbo ẹ̀ka ayé wa; ṣíṣe ìfẹ́ Ọlọ́run gbọ́dọ̀ jẹ́ àfojúsùn tí ó jẹ ọ́ lógún.

**b. O gbọ́dọ̀ wà ní ìfojúsùn**





Pinnu fún ore-ọ̀fẹ́ rẹ̀ kí ó bà lé ọ lórí, pinnu láti wọ ìjọba ọ̀run. Pinnu láti má pàdánù ẹ̀mí rẹ fún èṣù, ẹni tí ó wà ní àyíká rẹ láti já ẹ̀mí rẹ gbà. Jọ̀wọ́, wà ní ìmúrasílẹ̀ kí o sì pa ọkàn rẹ pọ̀ lórí irú ìpìlẹ̀ tí o n fi lélẹ̀ nínú Krístì Jésù. Báwo ni o ṣe n rin ọ̀nà àjò rẹ lọ sí ọ̀run?

**d. Ránṣe pe onímọ̀-ẹ̀rọ ayé rẹ láti sáájú, bí o ti n mọ búlọ́kù rẹ.**



Pàápàá bí o ti n gbé ìgbẹ́sẹ̀ kọ̀ọ̀kan, mímọlé ìpìlẹ̀ náà ní ohun tí n ṣe. Àwọn búlọ́kù tí à n mọ ni àwọn ìgbésẹ̀ tí à n gbé ní ìgbà tí à n kọ́ ìdílé wa èyí tí ó wà ní oríṣí ìsọ̀rí. Bí àpẹẹrẹ, yíyan olùrànlọ́wọ́ (ọkọ tàbí aya), iṣẹ́, ìpìlẹ̀ ìbáṣepọ̀ àti ìgbéyàwó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Fífi búlọ́kù kọ̀ọ̀kan lélẹ̀ lórí ìpìlẹ̀ wa ṣe pàtàkì. Èyí ni ó le sọ bí ilé náà yíò ti rí, èyí tí í ṣe ayé rẹ. **Òun nìkan ṣoṣo ni ó lè ṣe àgbékalẹ̀ ìgbé ayé àṣeyọrí fún ọ.**

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti tẹ̀lé e títí d'ójú àmì, kí o sì mu ní òkúnkúndùn; títẹ̀lé àti gbígbọ́ràn sí gbogbo ìtọ́ni rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ẹ̀rọ.

Ará, o kò lè dáa kọ́ nínú ọgbọ́n rẹ nìkan, Òun ni ayàwòrán àgbà. Ránṣẹ́ pe Ẹ̀mí Mímọ́ nítorí ó n bẹ lẹ́gbẹ̀ ẹ́ ọ̀dọ̀ rẹ.

Ohun tí mò n sọ ni wípé, Ìbáṣe pé o ti fi àkíyèsára òun ìrẹ̀lẹ̀ pè é gẹ́gẹ́ bí olùtùnú àti aṣáájú sínú gbogbo ẹ̀ka ayé rẹ; ayé àti ọ̀nà rẹ ìbá ti dára ju èyí lọ.



A kò lè tan Ọlọ́run, Ó mọ̀ ọ́ ju bí o ti mọ ara rẹ lọ. Ó n rí ọ bí o ti n jìjà gbara pẹ̀lú ayọ̀ ayé rẹ tí Ó ti gbé kalẹ̀ fún ọ láti ní gẹ́gẹ́bí ohun ìní rẹ. Ìwọ ni ó ni ayọ̀ rẹ, olùràpadà rẹ Jésù Krístì ti fi fún ọ, ṣùgbọ́n èṣù nbẹ ní àyíká rẹ ní ìgbà gbogbo, ó n jíjàkadì láti gbà á kúrò lọ́wọ́ rẹ.

**e. Ránṣe pe Ẹ̀mí Mímọ́, Olùrànlọ́wọ́ wa**

O kò gba Ẹ̀mí Mímọ́ lááyè ní kíkún. Olúwa ti fún wa ní olùrànlọ́wọ́ láti ṣàṣeyọrí nínú ayé. Ò n gbìyànjú, o sì n jà láti fẹ́ Ọlọ́run pẹ̀lú agbára, okun àti ipá rẹ, ṣùgbọ́n Ẹ̀mí Mímọ́ nìkan ló le ràn ọ́ lọ́wọ́.

Ohun tó mú kí Pétérù sẹ́ Jésù ni ẹ̀rù, bíbélì sì sọ wípé nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bà lé Pétérù, ó ṣetán láti kú fún Jésù Krístì.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ wa n wo ìdúró wa nínú Ọlọ́run pẹ̀lú ìwọ̀n ẹ̀bùn Ọlọ́run nínú wa. Rárá o! Kò rí bẹ́ẹ̀! Bíkòṣe ìwọ̀n èso Ẹ̀mí Mímọ́ nínú wa. Èso tí à n so ló ṣe pàtàkì.

Nígbàmíràn ẹ̀wẹ̀, a máa n lérò wípé ọjọ́ ọ̀la wa bọ́dọ̀ dára nítorí ẹ̀bùn tí a ní. Rárá, ìrànlọ́wọ́ kanṣoṣo tí a ní wà nínú Ẹ̀mí Mímọ́.

**Èso Ẹ̀mí Mímọ́**

Mo gbà ọ́ n'ìmọ̀ràn nítòótọ́, pé kí o so èso ti Ẹ̀mí Mímọ́, ó ṣe pàtàkì lọ́pọ̀lọpọ̀. Àwọn èso wọ̀nyí ṣe àkójopọ̀ irú ẹni tí o jẹ́ nípa ti ẹ̀mí àti nípa ti ara, ẹni tí o jẹ́ sí Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá rẹ àti sí gbogbo àwọn ènìyàn tí ó wà ní àyíká rẹ. Ìhùwàsí rẹ ni ó n darí rẹ láti kọ́ ayé rẹ àti ilé rẹ dáradára lórí Krístì àpáta.

**"Ṣùgbọ́n èso ti Ẹ̀mí ni ìfẹ́, ayọ̀, aláàfíà, ìpamọ́-ra, ìwà pẹ̀lẹ́, ìṣore, ìgbàgbọ́."** Galátíà 5:22.

Njẹ́ o ṣàkíyèsí pé Ìfẹ́ ni ó ṣe àkọ́kọ́ nínú gbogbo èso ti Ẹ̀mí Mímọ́?

Bíbélì sì sọ nínú ìwé Kọ́ríntìn kìn-ín-ní orí kẹtàlá ẹsẹ̀ kìn-ín-ní dé ìkẹjọ (1Kor 13:1-8) wípé:



**"Bí mo tilẹ̀ n fọ onírúuru èdè àti ti ángẹ́lì, tí èmi kò sì ní ìfẹ́, èmí dàbí idẹ tí n dún, tàbí bí kímbálì olóhùn gooro".**

**"Bí mo sì ní ẹ̀bùn ìsọtẹ́lẹ̀, tí mò sì ní oye gbogbo ohun ìjìnlẹ̀, àti gbogbo ìmọ̀; bí mo sì ní gbogbo ìgbàgbọ́ tó bẹ́ẹ̀ tí mo lè ṣí àwọn òkè nlá nípò, tí èmi kò sì ní ìfẹ́, èmi kò jẹ́ nkan."**

**"Bì mo sì n fi gbogbo ohun ìní mi bọ́ àwọn tálákà, bí mo sì fi ara mi fún ni láti sun, tí èmi kò sì ní ìfẹ́, kò lí èrè kan fún mi."**

**"Ìfẹ́ a máa mú sùúrù, a sì máa seun: ìfẹ́ kì í ṣe ìlara; ìfẹ́ kí I sọ̀rọ̀ ìgbéraga, kì í fẹ̀, Kì í hùwà àìtọ́, kì í wá ohun ti ara rẹ̀, a kì í mú u bínú, bẹ́ẹ̀ni kì í gbìrò ohun búburú,"**

**"Kì í yọ̀ sí àìsòdodo, sùgbọ́n a máa yọ̀ nínú òtítọ́;"**

**"A máa farada ohun gbogbo, a máa gba ohun gbogbo gbọ́, a máa retí ohun gbogbo, a máa fàyàrán ohun gbogbo."**

**"Ìfẹ́ kìí yẹ̀ láí; sùgbọ́n bí ó bá ṣe pé ìsọtẹ́lẹ̀ ni, wọn ó dópin; bí ó bá ṣe pé ẹ̀bùn ahọ́n ni, wọn ó dákẹ́; bí ó bá ṣe pé ìmọ̀ ni, yíò di asán."**

Àwọn ẹ̀bùn ẹ̀mí yíò lè dàgbà bí ó bá dàgbà nínú gbòngbò ìfẹ́. Bí o ṣe n rí àwọn ènìyàn tó yí ọ ká àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká rẹ kọ́ ni wọ́n ṣe rí. Bí ọkàn rẹ ṣe rí ni wọ́n ṣe rí ní ojú rẹ nítorí pé o kò gbá Ẹ̀mí Mímọ́ láyè láti wò wọ́n kí ó sì ràn ọ́ lọ́wọ́.

**Àdúrà**

Mo fẹ́ kí o bèérè lọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti àkókò yìí lọ. Àkókò agbára, ore-ọ̀fẹ́ àti kíkún fún Ẹ̀mí Mímọ́ ni a wà yìí. Ó wà lẹ́gbẹ̀ rẹ láti ràn ọ́ lọ́wọ́, bí o bá le ránṣẹ́ pè é. Ó ti ṣèlérí láti jẹ́ olùrànlọ́wọ́ wa kò sì lè kùnà. Jẹ́ kí á gbàdúrà, ó n bẹ ní ẹ̀gbẹ́ ọ̀dọ̀ rẹ, pè é sínú ayé rẹ. Ó n bẹ nítòsí rẹ nísinsìnyí.



ẹ. **Kíkọ́ ayé rẹ pẹ̀lú ìdánilójú àti Ìgboyà - ìgbàgbọ́**



- Gbé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó ní kí o gbé.
- Ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú rẹ̀ nínú ìdarí àti ìtọ́ni rẹ.
- Kò le sìṣe, Aláṣepé ni òun.
- Òun kò le ṣì ọ́ darí, tẹ̀lé e. Olùdarí tó dára jùlọ ni: yí ò sì darí rẹ sí ibi àṣeyọrí.

f. **Gbígbé nínú agbègbè rẹ**

**"Ẹni tí ó jókòó níbi ìkọ̀kọ̀ ọ̀gáọ́ògo ní yíò ma gbé abẹ́ òjìji olódùmárè."** Orin Dáfídì 91:1.

O gbọ́dọ̀ ma gbé ní agbègbè èyí tí ìpilẹ̀ tí ó dára tí ó sì yè koro gbé wà. Ìbárẹ́ ayé tó le já sí panṣágà ní àyè kò gbà.

## ORÍ KEJÌ

# WÍWÁ AGBÁRA FÚN IPA RERE

**"Ìbẹ̀rù OLÚWA ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ìmọ̀; ṣùgbọ́n àwọn aṣiwèrè gan ọgbọ́n àti ẹ̀kọ́."** Òwe 1:7.

**"Ìbẹ̀rù OLÚWA ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ọgbọ́n: àti ìmọ̀ ẹni-mímọ́ li òye."** Òwe 9:10.

O gbọ́dọ̀ ní ìmọ̀ ohun kan kí o tó lè sọ̀rọ̀ nípa lílo ohun tí o mọ̀. Ìbẹ̀rù Olúwa yíò tọ́ ọ sí ìmọ̀ (níní àwọn kókó ọ̀rọ̀), sí ọgbọ́n (lílo àwọn kókó ọ̀rọ̀ yìí sí ìgbé ayé). Nígbànáà ni ìwọ yíò jọba ayé rẹ, ìwọ yíò sì ní àṣeyọrí. O gbọ́dọ̀ mọ̀ wípé, ìmọ̀ tí o nílò láti ní ipa lórí ayé rẹ kì í ṣe ti ìwé kíkà, ìwà ní àwùjọ àti ti òṣèlú tàbí ti orísun ìmọ̀ míràn nìkan, bíkòṣe ìmọ̀ Ọlọ́run.

Ní wíwá ìmọ̀ Ọlọ́run àti ti bíbélì láti darí ayé rẹ, o ní láti ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run. Láti ni



ìmọ̀ fún àṣeyọrí àti àlùyọ, láti ní ìmọ̀ fún àlàáfíà àti ìrẹ́pọ̀ nínú àwọn àjọṣepọ̀ rẹ, o ní láti bẹ̀rù Ọlọ́run.

- Ṣe ohun tí Jésù yíò lè ṣe, kí o sì kọ àwọn ohun tí kò lè ṣe sílẹ̀.
- Dà bíi Jésù nínú gbogbo iṣe àti ìwà rẹ.
- Fi ẹ̀dá Ọlọ́run hàn nínú ìṣesí rẹ.

Ìgbà tí o bá tó bẹ̀rù Ọlọ́run ni o ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ ìrìn àjò lọ sí ìlú ìmọ̀, ká má wà á sọ ti ọgbọ́n níní. Nítorí láìsí ìmọ̀, o kò lè ní ọgbọ́n. Bí o kò bá sì ní ìmọ̀ ohun kan, o kò lè jọba lórí nkan náà.

Nípa ọgbọ́n Ọlọ́run nìkan ni o lè jọba ayé rẹ. O gbọ́dọ̀ wá ìmọ̀ Ọlọ́run láti ní ọgbọ́n àti darí àwọn orílẹ̀-èdè.

Bí o bá bẹ̀rù Ọlọ́run, ó túmọ̀ sí wípé o ti fi ìpìlẹ̀ lélẹ̀ èyí tí í ṣe wíwá ìmọ̀. Ó túmọ̀ sí pé o mọ àṣírí ohun tí o nílò láti lé se àṣeyọrí, àlùyọ, ìṣẹ́gun àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.

## ỌGBỌ́N

Ìtumọ̀ ọgbọ́n ju pé kí á mọ ohun púpọ̀ lọ. Ó jẹ́ ìṣesí pàtàkì tí ó níṣe pẹ̀lú gbogbo ẹ̀yà ìgbé ayé ènìyàn. Ìpìlẹ̀ ìmọ̀ ni láti bẹ̀rù Ọlọ́run.

Láti bẹ̀rù Ọlọ́run túmọ̀ sí pé:

- Láti bu ọlá àti ọ̀wọ̀ fún Ọlọ́run.
- Láti máa gbé nínú ọwọ́ agbára rẹ̀.
- Láti gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ rẹ̀ (ní kíkún).
- Láti kórìra ibi, ìgbéraga àti ìrera. Òwe 8:13

Láti jọba lórí àwọn elòmíràn, o gbọ́dọ̀ lè jọba lórí ayé ara rẹ̀. O kò lè jọba lórí ayé rẹ dáradára bí o kò bá tẹ̀lé ìlànà àti òfin láti ní ọgbọ́n. Láti ní ọgbọ́n, o gbọ́dọ̀ ní òye ohun púpọ̀ bákannáà àti ní òye jẹ́ àti ní ìmọ̀. O gbọ́dọ̀ bẹ̀rù Olúwa fún ọ láti ni ìmọ̀.

O nílò ọgbọ́n Ọlọ́run nínú àwọn àjọṣepọ̀ rẹ, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, ìjìyà yíò wà nínú àjọṣepọ̀. O



kò sì lè ní ọgbọ́n Ọlọ́run láìní ìmọ̀ rẹ̀. Bíbélì wípé "Ìbẹ̀rù Ọlọ́run ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ìmọ̀," nítorí náà bẹ̀rù Ọlọ́run.

**Kíyèsí:** Ohun kékeré tí yíò ná ọ láti lè ní àṣeyọrí, kí o sì jọba lórí ayé rẹ. Sá ti gbọ́ràn!

Nínú àjọṣepọ̀ gbogbo, a gbọ́dọ̀ fi ìfẹ́ hàn, ìfijì àti ìhùwà tí ó pegedé. Nígbàkúgbà tí a bá yan ọ̀nà Ọlọ́run, Òun á fún wa ní ọgbọ́ n. Ọ̀rọ̀ rẹ̀, bíbélì mímọ́ ndarí wa láti gbé ìgbé ayé tí ó tọ́, ní ìbáṣepọ̀ tí ó tọ̀nà, àti gbígbé ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà. Èyí túmọ̀ sí pé láìsí ìbẹ̀rù Ọlọ́run nínú rẹ, o kò lè wà nínú ìbáṣepọ̀ aláṣeyọrí. Bí o kò bá sì ní ìbáṣepọ̀ tí ó dára tí ó sì ní àṣeyọ́rí, o lè nira fún ọ láti gbéyàwó, bí o bá sì gbéyàwó, ayọ̀ kì yíò sí nínú irú ìgbéyàwó bẹ́ẹ̀.

Nítorí náà, ohun tí à n sọ ni pé, láì ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run nínú ohunkohun tí o bá ṣe, o kò lè ní àṣeyọrí; bí kò bá sí ìbáṣepọ̀ aláyọ̀ àti ìdùnnú, kò lè sí ìdílé aláyọ̀ tó ní

àṣeyọrí. Mo pá ní àrọwà gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ti wí; pé kí o wá ọgbọ́n láti darí àti láti ní ipa nlá lórí àwọn ìbáṣepọ̀ rẹ àti lórí ayé rẹ.

Apá kejì Owe 1:7 sọ wípé: "**ṣùgbọ́n àwọn aṣiwèrè gan ọgbọ́n àti ẹ̀kọ́**."

Aṣiwèrè (bí bíbélì ti sọ)

- Ẹnikẹ́ni tí ó bá n ṣe bí ẹni tí ó mọ ohun gbogbo.
- Ẹni tí ó bá ni èrò tí a kò fìdí rẹ̀ múlẹ̀ nípa ohun gbogbo.
- Ẹni tí kò bá gba ohun títun.
- Ẹni tí o bá kọ ìbáwí.
- Ẹni tí kò fẹ́ kẹ́kọ̀ọ́.

Máṣe jẹ́ ẹni tí ó mọ ohun gbogbo, máa gbọ́ ìmọ̀ràn àwọn elòmíràn pàápàá àwọn tí ó mọ̀ ọ́ dájú tí ó sì lè fún ọ ní ìmọ̀ràn tí ó péye. Bíbélì pè ọ́ ní aṣiwèrè tí o bá kọ ọgbọ́n àti ìtọ́ni; nígbàtí èṣù bàbá gbogbo aláìsòótọ́ bá tilẹ̀ tàn ọ́ láti má bẹ̀rù



Ọlọ́run; nígbàtí o kò bá ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run nínú rẹ mọ́; nígbàtí o bá ti mọ̀ọ́mọ̀ n dá ẹ̀ṣẹ̀, o mọ̀ọ́mọ́ dá ẹ̀ṣẹ̀ àgbèrè àti panṣágà. Ní ìgbàmíràn, o sun ẹ̀kún fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ, ṣùgbọ́n o tún mọ̀ọ́mọ̀ padà sínú rẹ̀, bíbélì pè ọ́ ní aṣiwèrè, ó yẹ kí o mọ̀ wípé, a kò lè gan Ọlọ́run. Òun ni Ọlọ́run, aṣẹ̀dá ẹ̀mí rẹ. Òun ni ó dá ọ̀run àti ayé. A kò lè tàn Án; Òun ni ó mọ ohun gbogbo.

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ ọ̀pọ̀ ewu tó wà lórí ayé rẹ fún àìní ìbẹ̀rù Ọlọ́run. Yíò mú kí ayé rẹ kí ó má ní ìtumọ̀, yíò sì dàbí pé o kò mọ bí o ó ṣe ṣètò ọjọ́ ọ̀la rẹ. Mọ̀ wípé, òtítọ́ ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, nítorí náà, o nílò láti bẹ̀rù Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá rẹ, ẹnití ó lè gbé sókè, kí ó sì rẹ̀ sílẹ̀.

## EWU TÓ WÀ NÍNÚ KÍKỌ̀ LÁTI WÁ ỌGBỌ́N ỌLỌ́RUN - Òwe 1:24-33

24. **"Nítorí tí èmí pè, tí ẹ̀yín sì kọ̀; tí èmí na ọwọ́ mi, tí ẹnìkan kò sì kàá sí;**
25. **Ṣùgbọ́n ẹ̀yín ti ṣá gbogbo ìgbìmọ̀ mi tì, ẹ̀yin kò sì fẹ́ ìbáwí mi:**

26. **Èmí pẹ̀lú ó rẹ́rìn-ín ìdàmú yín; èmi ó ṣe ẹ̀fẹ̀ nígbàtí ìbẹ̀rù yín bá dé;**

27. **Nígbàtí ìbẹ̀rù yin bá dé bí ìjì, àti ìdàmú yín bí àfẹ́yíkáọ̀ìjí; nígbàtí wàhálà àti àrodun bá dé sí yín.**

28. **Nígbànáà ni ẹ̀yin ó ké pè mí, ṣùgbọ́n èmi kì yíò dáhùn; wọn ó ṣàfẹ́rí mi ní kùtùkùtù, sùgbọ́n wọn kì yíò rí mi:**

29. **Nítorí tí wọ́n kórìra ìmọ̀, wọn kò sì yan ìbẹ̀rù OLÚWA:**

30. **Wọn kò fẹ́ ìgbìmọ̀ mi: wọ́n gan gbogbo ìbáwí mi.**

31. **Nítorí náà ni wọn ó ṣe ma jẹ nínú èrè ìwà ara wọn, wọn ó sì kún fún ìmọkímọ̀ wọn.**

32. **Nítorí pé ìrora àwọn aláìmọ̀kan ni yíò pa wọ́n, àti àláàfíà àwọn aṣiwèrè ni yíò pa wọ́n run.**

33. **Ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni tí ó bá fetísí mi yíò ma gbé láìléwu, yíò sì farabalẹ̀ kúrò nínú ìbẹ̀rù ibi."**



Bí o kò bá bẹ̀rù rẹ̀, dájúdájú ìwọ yíò ṣe si Í.

**"Ṣùgbọ́n ẹni tí ó sẹ́ mi, o ṣe ọkàn ara rẹ̀ níkà: gbogbo àwọn tí ó kórìra mi, wọ́n fẹ́ ikú."** Òwe 8:36.

## ÀNFÀNÍ TÓ WÀ NÍNÚ YÍYÀN LÁTI BẸ̀RÙ OLÚWA

Ìwọ yíò ma gbé ní àìléwu, ibi yíò jìnà sí ọ.

**"Ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni tí ó bá fetí sí mi yíò ma gbé láìléwu, yíò sí farabalẹ̀ kúrò nínú ìbẹ̀rù ibi."** Òwe 1:33.

Ìwọ yíò ní ìmọ̀ràn rere àti ọgbọ́n tí ó yè.

**"Tèmi ni ìmọ̀ àti ọgbọ́n tí ó yè: èmi li òye; èmi ni agbára."** Òwe 8:14.
Òun yíò fún ọ ní okun láti mòye. Òwe 8:14b.
Ìwọ yíò ṣe àkóso, o ó sì jọba lórí ayé rẹ.
**"Nípasẹ̀ mi li ọba n ṣe àkósò, tí àwọn olóri sì n lànà òtítọ́. Nípasẹ̀ mi li àwọn ìjòyè n ṣolórí, àti àwọn olótìítọ́, àní gbogbo àwọn onídajọ́ ayé."** Òwe 8:15-16

Òwe 8:17a, "**Mo fẹ́ àwọn tí ó fẹ́ mi**", bí àpẹẹrẹ, obìnrin tí ó bá fẹ́ràn ọkọ rẹ̀, yíò bẹ̀rù rẹ̀.

**Àkíyèsí:** Bí o bá fẹ́ràn Ọlọ́run, ìwọ yíò bẹ̀rù rẹ̀. Bí o bá fẹ́ Ọlọ́run nípa bíbẹ̀rù rẹ̀, Òun yíò fẹ́ràn rẹ, bí Ọlọ́run bá sì ti fẹ́ràn rẹ, Ó lè ṣe ohunkóhun nítorí rẹ.

"...èmí sì ti fẹ́ ọ, mo ti fẹ́ ọ, nítorí náà èmi ó fi ènìyàn rọ́pò rẹ, àti ènìyàn dípò ẹ̀mí rẹ," Ìsaiah 43:4c. Òun yíò sì fẹ́ràn rẹ débi wípé, yíò fi ẹ̀mí rọ́pò èmí nítorí rẹ.

Ìwọ yíò ní ọrọ̀ àti ọlá, ọrọ̀ dáradára àti òdodo ni ìwọ ó ni. "Ọrọ̀ àti ọlá n bẹ lọ́wọ́ mi, àní ọrọ̀ dáradára àti òdodo," Òwe 8:18.

Òun yíò tọ́ ọ nípa òdodo. "Èmí n rìn lí ọ̀nà òdodo," Òwe 8:20a

Òun yíò sì mú kí o jogún ìní, yíò sì kún ìṣura rẹ.



**ÌMỌ̀RÀN**

**"Ọmọ mi, gbọ́ ẹ̀kọ́ bàbá rẹ, kí ìwọ kí ó má sì kọ òfin ìyá rẹ sílẹ̀,"** Òwe 1:8. **Gbọ́ tirẹ̀, Ẹlẹ́dàá rẹ n pè ọ́ nísinsìnyí, Ó lè gba ẹnikẹ́ni tí ó bá gbọ́ tirẹ̀ là. Jọ̀wọ́ ara fẹ fún Un, Òun ló le gbà là tí ó sì lè tú ọ sílẹ̀.**

**"Èrè mí ta wúrà yọ, nítòótọ́, ju wúrà dáradára lọ, àti ọrọ̀ mi ju fàdákà àṣàyàn lọ."** Òwe 8:19.

Yíyàn láti bẹ̀rù Olúwa ní èrè ju èrè yòówù tí o lè ní lọ́kàn láti rí níbòmíràn lọ. Kò ṣ é fi wé wúrà pàápàá.

**ORÍ KẸTA**

# ÀWỌ́N KÓKÓ ÀṢÍRÍ/ÈRÒ ÌPARÍ

1. O kò lè ṣe oriire pé kí Ọlọ́run fún ọ ní ẹnití o dára púpọ̀, nígbàtí ìwọ fúnra rẹ ò dára (ẹgbẹ́ ẹyẹ l'ẹye n wọ́ tọ̀). Ọlọ́run ní ìfẹ́ ẹnìkejì bákannáà tí kò fi lè fún ọ, kí á má baà fi ìṣura ṣòfò. Ẹ lè ní àwọn ìyàtọ̀ tí yíò já sí ìjàngbọ̀n. Nítorí náà, ṣe rere, di ara rẹ ní àmùrè, kí o sì múra fún ìyípadà.
2. Máṣe gbé ìyàwó nítorí pé àánú n ṣe ọ́. Kíyèsára ní ṣíṣe ìdájọ́ àti ìdánwó. Máṣe tan ara rẹ, a kò lè gan Ọlọ́run.
3. Jẹ́ onírẹ̀lẹ̀ láti fẹ́ ẹni yòówù tí Ọlọ́run bá mú wá sí ọ̀nà rẹ. Mọ̀ wípé Ọlọ́run ní ìmọ̀ jù ọ́ lọ. Ó kàn



nílò láti rẹ ọkàn rẹ sílẹ̀ kí Ó lè fún ọ ní èyí tí ó wù ú fún ayé rẹ.

4. Ọlọ́run kì yíò fún ọ ní nkan ojúlówó tí kò tọ́ sí ọ tàbí tí o kò ṣiṣẹ́ fún. N kò sọ wípé Òun kò lè bùkún ọ pẹ̀lú aya tàbí ọkọ rere, ṣùgbọ́n o nílò láti ri gẹ́gẹ́ bí ohun tí o fẹ́ fún aya tàbí ọkọ. Látàrí èyí, mú ara rẹ dàgbà dé ibi ìwọ̀n ti ẹ̀mí tí o fẹ́ kí aya tàbí ọkọ rẹ wà.
5. Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ pé àwọn ilẹ̀kùn ìbùkún àti àlùyọ kan wà tí o kì n ṣi ṣàájú ìgbéyàwó bíkòṣe láti ọjọ́ ìgbéyàwó rẹ. Nítorí náà, má ṣe sọ wípé o gbọ́dọ̀ kọ́ ilé alárà tàbí ra ọkọ̀ bọ̀gìnnì kí o tó ṣe ìgbéyàwó.
6. Ìpìlẹ̀ tó dájú nínú Krístì. Bíbélì wípé "bí ìpìlẹ̀ bá bàjẹ́, kíni kí olódodo kí ó ṣe?" Ìbáṣepọ̀ rẹ yíò ṣiṣẹ́ kìkì bí o bá kọ lórí àpáta tííṣe Krístì. Ìpìlẹ̀ ìbáṣepọ̀ tàbí ìgbéyàwó rẹ níí ṣe púpọ̀ pẹ̀lú irú ìdílé tí ìwọ yíò ní.

Njẹ́ ò n kọ́ ìbáṣepọ̀ rẹ lórí ẹ̀tàn, irọ́, ìdíbọ́n, ìbálòpọ̀ òdì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Jẹ́ kí n sọ fún ọ, obìnrin tàbí okùnrin yìí kannáàn ni kò ní gbà ọ́ gbọ́ bí ẹ bá tilẹ̀ fẹ́ ara yín. Nítorí pé yíò máa ni lọ́kàn pé ohun tó ba mú ọ ṣee sáájú, o lé e tún ṣe bẹ́ẹ̀ lẹ́yìn ìgbéyàwó pẹ̀lú elòmíràn.

Mo rọ̀ ọ́ láti kọ́ ìbáṣepọ̀ rẹ lórí òtítọ́, ojúlówó ìfẹ́, ìṣòdodo, ìwà rere àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìbálòpọ̀ ṣáájú ìgbéyàwó máa n jẹ́ kí ó pàdánù ọwọ́ rẹ. ìbálòpọ̀ òdì ti ba ayé ọ̀pọ̀lọpọ̀ jẹ́.

7. Ó tún ṣe é ṣe pé kí o má nífẹ̀ẹ́ ẹni tí Ọlọ́run ní kí o fẹ́ lákọ̀ọ́kọ́. Ó lé má jẹ́ ìfẹ́ àkọ́kọ́ fojúkanra, ó le jẹ́ ìfẹ́ tí o nílò láti mú dàgbà ṣáájú ìgbéyàwó rẹ. O gbọ́dọ̀ fẹ́ràn ọkùnrin tàbí obìnrin náà nítorí Krístì. Jẹ́ kí Krístì kí ó yàn fún ọ. Yíyàn tirẹ̀ ni ó dára jùlọ, tọ́ Jésù wò, ìwọ yò sì ma rántí ọjọ́ òní fún rere nínú ayé rẹ. Àmín.



Máṣe ṣe àṣìṣe ní fífi ìfẹ́ wé ìṣesí ìfi ìfẹ́ hàn. Ènìyàn lè jẹ́ ẹni tí ó dára nípa ẹ̀dá rẹ̀ ní fífi ìfẹ́ hàn, kí ó sì má ní ìfẹ́ rẹ rárá ní ọkàn rẹ̀.

8. Bí àjọṣepọ̀ rẹ pẹ̀lú Ọlọ́run bá wà ní digbí, ohun gbogbo nípa rẹ, ẹ̀kọ́ rẹ, àṣeyọrí iṣẹ́ rẹ, ìbáṣepọ̀ rẹ, ìgbéyàwó rẹ yíò bọ̀ sípò fúnra wọn.
9. O lè ti èṣù kúrò ní ọ̀nà ìgbéyàwó rẹ.

**Ìbéèrè**

Njẹ́ o fẹ́ ṣe ìgbéyàwó lọ́dún yìí? Nígbàwo lo fẹ́ kò dé sí? Lọ sínú àkọsílẹ̀ ọjọ́, mú ọjọ́ tí ó wù ọ́ báyìí. Èyí nì, ọjọ́ ìgbéyàwó rẹ.

## ÀWỌN ÀṢÍRÍ LÁTI MÙ ỌJỌ́ NÁÀ WÁ SÍ ÌMÚṢE

Fi ayé rẹ ní kíkún fún Jésù Krístì. Pinnu láti gbé ìgbé ayé rẹ fún Jésù nìkan nípa pé ìwọ kọ́ ni o ni èròngbà tàbí èrò ọkàn tirẹ.

Fún Un ní gbogbo ohun tí ó bérè lọ́wọ́ rẹ láti àkókò yìí lọ.

**Àkíyèsí:** Yálà o tilẹ̀ wà nínú ìbáṣepọ̀ tí kìí ṣe ìfẹ́ rẹ báyìí, tí o sì mọ̀ dájú. Jọ̀wọ́ rẹ̀ fún Un nítorí ìmúṣe májẹ̀mú titun ti ọjọ́ ọ̀la tí ó dára tí o ti bá Ọlọ́run dá lónìí.

**Ìkóraẹni ní Ìjánu:** Ó ṣe pàtàkì pé kí o kó ara rẹ ní ìjánu nínú eré ẹ̀ṣẹ̀. Jẹ́ kí n sọ fún ọ, àwọn ànfààní ẹ̀tàn kan wà nínú ẹ̀ṣẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, èyí tí ọkùnrin n gbádùn ìbálòpọ̀, tí obìnrin sí n gbádùn owó láti ra aṣọ, bàtà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó dìgbà tí o bá kó ara rẹ ní ìjánu nínú gbogbo àwọn ìgbádùn ìgbà díẹ̀ wọ̀nyí, kí o tó le ní ìgbádùn èyí tí ó jẹ́ ojúlówó nínú Krístì Jésù. Mo gbà á ládùúrà wípé o kò ní pàdánù ní orúkọ Jésù. Àmín.

O nílò láti fi ìpìlẹ̀ rere lélẹ̀ nínú Krístì Jésù, torí ó níṣe pẹ̀lú àṣeyọrí rẹ gẹ́gẹ́ bí ọ̀dọ́; nítorí náà, o ní láti fi ayé rẹ fún Olúwa wa Jésù Krístì ní kánkán. Ó tún jẹ́ ohun pàtàkì pé kí o máṣe tan ara rẹ kí o ba lè ní ọjọ́ ọ̀la tó ní àbò. Mo sì gbàdúrà pé kí oore-ọ̀fẹ́ Olúwa wa Jésù Krístì kí ó tó fún ọ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.